Yoruba | Yorùbá

NYC Mayor's Office of Immigrant Affairs

# ÀWỌN OHUN ÈLÒ FÚN ÀWỌN OLÙṢÍWỌ̀LÚ NÍ NEW YORK

## LÁÌ KA IPÒ ÌṢÍWỌ̀LÚ RẸ SÍ, ÌLÚ NEW YORK WÀ NÍBÍ LÁTI ṢE ÌRÀNWỌ́.

### Ìrànlọ́wọ́ Òfin Ìṣíwọ̀lú

**Fún ìrànlọ́wọ́ òfin ìṣíwọ̀lú láìsanwó àti láìséwu, pe 800-354-0365**, láti Ọjọ́ Ajé sí Ọjọ́ Ẹtì, 9AM sí 6PM.

### Káàdì Ìdánimọ̀ New York

**Bèèrè fún IDNYC**, káàdì ìdánimọ ọ̀fẹ́ ti ìlú fún gbogbo àwọn olùgbé Ìlú New York tí wọ́n ti pé ọmọ ọdún 10 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Ṣe àtúnṣe lórí ayélujára tàbí ṣe àdéhùn láti forúkọsílẹ̀, **pe 311** tàbí kàn sí **nyc.gov/idnyc**

### Àwọn Kíláàsì Ẹ̀kọ́ Èdè Gẹ̀ẹ́sì

Ṣe àwọn ẹ̀kọ́ èdè **Gẹ̀ẹ́sì ọ̀fẹ́** nígbàkigbà, níbikíbi. Kàn si **wespeaknyc.cityofnewyork.us** fún àlàyé si.

### Ìtọ́jú ìlera

**NYC Health + Hospitals (H+H)** lè pèsè àbójútó pàjáwìrì, àbójútó ìlera tó ṣe kókó, àyẹ̀wò ara ẹni, àjẹsára, àti jù bẹ́ẹ̀ lọ. **Pe 1-844-NYC-4NYC (1-844-692-4692) láti darí rẹ sí ibùdó tó sún mọ́ ọ jùlọ.** Láti forúkọ sílẹ̀ nínú ètò ìbánigbófò ìlera, títí kan ètò ìbánigbófò ìlera ètò **NYC Care** pe, **646-NYC-CARE (646-692-2273)** tàbí kàn sí **nyccare.nyc**

### Ìlera Ọpọlọ

Fún àtìlẹ́yìn bòókẹ́lẹ́ àti àwọn ìsopọ̀ pẹ̀lú ètò ìtọ́jú ìlera ọpọlọ àti àwọn ohun èlò ìmúlò oògùn olóró, pe **888-692-9355 or 988**, tàbí tẹ **WELL sí 65173.** Àwọn ará New York lè ṣàbẹ̀wò sí **nyc.gov/mentalhealthaccess** fún àwọn ohun èlò tí ó ní èdè púpọ̀ lórí àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ ní Ìlú New York, tàbí lo ìwé-ìmọ̀ orí ayélujára Ìlú New York 988 ní **nyc.gov/mentalhealthservices** láti wá àwọn iṣẹ́ ìlera ọpọlọ.

### Àwọn pàjáwìrì

**Nínú pàjáwìrì, pe 911.** Ìṣẹ̀lẹ̀ pàjáwìrì ni ipò èyíkéyìí tó bá nílò ìrànlọ́wọ́ ojú ẹsẹ̀ látọ̀dọ̀ àwọn ọlọ́pàá, ẹ̀ka panápaná, tàbí ọkọ̀ ìwòsàn. **Lójú òfin, Ẹ̀ka Ọlọ́pàá Ìlú New York (New York City Police Department) kò leè béèrè nípa ipò ìṣíwọ̀lú ti àwọn tó lu ìjàmbá ìwà ọ̀daràn, àwọn ẹlẹ́rìí, tàbí àwọn ènìyàn míràn tí ó béèrè fún ìrànlọ́wọ́.**

### Ẹ̀kọ́ Ìjọba

**Gbogbo àwọn ọmọdé ìlú New York tí ọjọ́ orí wọn wà láàárín ọdún 4 sí 21 lè lọ sí ilé ìwé ìjọba.** Láti forúkọsílẹ̀, kàn sí **schools.nyc.gov/fwc** tàbí kí o **pe 311.**

### Àwọn Ohun Àmúṣọrọ̀ àti Ìsọfúnni Ìlú Gbogboogbò

Ṣe o nílò láti wọlé sí àwọn ohun àmúṣọrọ̀ ìlú àbí o fẹ láti ṣe ìfisùn ìṣòro kan? Pe **311** tàbí ṣàbẹ̀wò sí **portal.311.nyc.gov**

### Ojú Òpó Ìpè Àjọ Tó ń Rísí Olùṣíwọ̀lú Ìlú New York

**Pè wá lórí ojú òpó ìpè wa ní 212-788-7654** láti Ọjọ́ Ajé sí Ọjọ́ Ẹtì, 9AM sí 5PM, tàbí fi imeeli ránṣẹ́ sí **askmoia@cityhall.nyc.gov**

Mayor's Office of Immigrant Affairs

# ÀWỌN OHUN ÈLÒ FÚN ÀWỌN OLÙṢÍWỌ̀LÚ NÍ NEW YORK

## LÁÌ KA IPÒ ÌṢÍWỌ̀LÚ RẸ SÍ, O NÍ ÀWỌN ẸTỌ́.

### Yàgò fún Jìbìtì Ìṣíwọ̀lú

Bí o bá nílò ìmọ̀ràn nípa ọ̀fin ìṣíwọ̀lú, agbẹjọ́rò tó ní ìwé àṣẹ tàbí aṣojú tí Ẹ̀ka Ìdájọ́ (Department of Justice, DOJ) fọwọ́ sí nìkan ni kí ó bá sọ̀rọ̀. O lè rí àkọsílẹ̀ àwọn olùpèsè tí a fọwọ́ sí tí a sì mọ̀ ní **nyc.gov/immigrationfraud**

### Àwọn ẹ̀tọ́ pẹ̀lú Ìgbófinró Ìṣíwọ̀lú

Ìlú New York kì í gbé ìgbésẹ̀ ìgbófinró ìṣíwọ̀lú. Tí àwọn òṣìṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ ìgbófinró ìṣíwọ̀lú bá tọ̀ ọ́ wá, o ní ẹ̀tọ́. Kàn sí **nyc.gov/knowyourrights** tàbí pe ojú òpó ọ̀fin ìṣíwọ̀lú ọ̀fẹ́ ní **800-354-0365**

### Àwọn Ẹ̀tọ́ Àwọn Òṣìṣẹ́

O ní ẹ̀tọ́ sí owó ìsinmi nítorí àìsàn, owó oṣù tí ó kéré jù, owó òṣìṣẹ́ àfikún àkókò àti púpọ̀ sí i lábẹ́ ọ̀fin Ìlú New York. Lọ sí **nyc.gov/workers** fún àwọn ohun àmúṣọrọ̀ tàbí pe **212-436-0380**

### Ṣe Ìfisùn Ẹ̀yàmẹ̀yà

Ìfòòró ẹni àti ẹ̀yàmẹ̀yà kò bófin mu lábẹ́ Òfin Ẹ̀tọ́ Ọmọniyàn ìlú New York. Láti ṣe ìfisùn ẹ̀yàmẹ̀yà, jọ̀wọ́ pe **212-416-0197** tàbí kàn sí **nyc.gov/reportdiscrimination**

### Ìdáàbòbò Lójú Ìwà Ipá Nínú Ilé

Ìlú New York wà níbí láti ràn ọ́ lọ́wọ́ tí o bá ń jìyà. O lè lọ sí **nyc.gov/nychope** tàbí kí o pe Ojú Òpó Ìwà Ipá Nínú Ilé ti Ìlú New York ní **800-621-HOPE**

### Àwọn Ẹ̀tọ́ Àwọn Ayálégbé

Ṣé o nílò ìrànlọ́wọ́ lórí àwọn ọ̀ràn tó ní í ṣe pẹ̀lú ìlénìnílé tàbí onílé rẹ? Lọ sí **nyc.gov/tenantprotection** tàbí pe **311** kí o sì sọ **"ténant helpline" (ojú òpó ayálégbé)** fún ìrànlọ́wọ́ ọ̀fin lọ́fẹ̀ẹ́

### Ẹ̀tọ́ sí Ibi Ìsádi

O ní ẹ̀tọ́ láti béèrè ibi ìsádi tí o bá ní ìṣòro àìrílégbé. Wá àwọn iṣẹ́ ibi ìsádi nípa lílọ sí ibùdó tí Ẹ̀ka Àwọn Iṣẹ́ Àìrílégbé (Department of Homeless Services, DHS). Mọ̀ síwájú sí i nípa pípe **311**

### Ààbò Oníbàárà

Ṣé o ní i ìṣòro pẹ̀lú ilé iṣẹ́ okòòwò kan? Gẹ́gẹ́ bí oníbàárà, o ní àwọn ẹ̀tọ́. Ṣe àròyé kàn nípa kíkàn sí **nyc.gov/consumers** tàbí pe **311**